**Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School**

**Ose Karunlelogoji: Osu Kokanla Ojo Karun, 2017**

**Akori Oro: Olorun ni ki o fe kise aiye** –Apa Keji

**Eko kika: 1 Johannu 2: 12-17**

Ao tesiwaju nipa siso oro nipa ife ti Olorun Olodumare ni fun awa eda-enia lati igbati a ti fi idi aiye kale.

**Ife Olorun fun awa eda-enia**

E mase jeki a tan yin, awon ohun-asan aiye yi bere ninu aiye beni won yio si dopin ninu aiye yi kanna. Awon wonyi ko wulo ninu orun nibiti o ti ngbero lati lo aiyeraiye re, nitorina e mase feran aiye tabi awon ohun ti mbe ninu re, eyiti nmu idalebi nikan wa lati odo Baba wa ti mbe ni orun. E mase ni ife awon ohun mere-mere ati adidun ati ifekufe ti mbe ninu aiye, nitoripe won ko ni ere niwaju Olorun, bikose ki won mu idajo wa si inu aiye eda-enia ni aiye-ti-mbo.

**A da enia ni aworan Olorun:** Olorun ni ife awa omo-enia pupo debipe o da wa ni aworan on tikara Re. O si se wa ni olu ati asayan larin gbogbo eda ise-owo Re. A kowe re wipe Olorun da enia li aworan re, nitori Ife ti o ni si wa **Genesisi 1: 27**. Ona kan soso ti a fi le te Olorun lorun, ni pe ki a ni ife Re pelu gbogbo aiya wa, ati gbogbo okan wa, ati gbogbo agbara wa. Nitorina, mase ni'fe aiye bikose ki o ni'fe Olorun ti o le fi ola ati oro gegebi ohun-ini fun awon ti o ni ife Re; ti yio si kun ile-isura nwon laisi laala tabi ibanuje. O nilo lati ni ife **eda ti o ju gbogbo eda lo**, ti o le fi ire ati ayo be aiye re wo; ti yio si fi ohun-rere kun ile-isura re. Olorun nikan ni eda-alaaye ti o le pese fun awon aini enikeni ti o ni ife Re, ti yio si fun nwon ni ola-nla pelu **Owe 8: 21**. Mase fi ife re dun Olorun sugbon ni ife Re gegebi ife-ailopin Re si o.

**Olorun fe wa pelu ifeni aiyeraye:** Yala a gbagbo tabi a ko gbagbo, Olorun ni ife awon enia Re, papa-julo awon ti o ni ife Re ninu ookan aiya won, O si fe nwon pelu ifeni aiyeraye. Olorun si fi ife-aisetan ati iyonu pa ore-ofe mo, fun iru awon ti o ni ife Re **Jeremiah 31: 3**. Bi o ba fe ki Olorun fe o pelu ife-titi-lai, ki Oluwa si tesiwaju ninu otito ati ododo Re si o, mase fe aiye. Idi

niyi ti Iwe mimo se so wipe “Ninu eyi ni ife wa, ki ise pe awa fe Olorun, sugbon on fe wa, o si ran Omo Re lati je etutu fun ese wa.” **1 John 4: 10**. Bi Olorun ati Eleda wa ba le ran Omo Re lati fi se irubo, ti o si ko ese wa lo, nitori ife ti o ni si wa: o ye ki awa na ni ife Re pada, ki a masi se fe aiye.

**Olorun ti pese anu, majemu ati ore-ofe sile:** Olorun ma nna owo anu ati ore-ofe jade nigbagbogbo si iru awon ti o fi tokantokan tele. O je ojuse Oluwa lati  ma fi anu ati oju-rere pelu ore-ofe han si gbogbo enia ti nwon ba ni ife Olorun ati oruko Re **Orin Dafidi 119: 132**. Bi o ba fe ki Olorun fi ogo Re han ninu aiye re, o ni lati ni ife Re; nitoripe eyi je eje Olorun si gbogbo awon ti nwon ni ife oruko Re. Olorun tun ma npa majemu ati anu mo fun awon ti o fe e, ti nwon si pa awon ofin Re mo **Nehemiah 1: 5**. O ni lati fe Olorun, ki o ba mu awon ileri Re se ninu aiye re, ki o si le se o logo. Mase feran aiye, bi o ba fe ki Olorun pa majemu ati anu mo fun o.

Ma ranti ni igbagbogbo wipe Olorun ni ife re, nitoripe iwo na ni’fe Re, o ko si feran aiye. Enikeni ti o ba fi tinutinu wa Olorun yio si ri i **Owe 8: 17**.

## Awon afihan Ife Olorun

Awon afihan ife-ijinle ti Olorun ni fun awa eda-enia wa ni ibigbogbo ni ayika wa. Elo ni a san fun afefe ti a nmi sinu-sode? Tani a san owo ojo ti nro ati orun ti nran lati mu awon irugbin dagba fun u? A kowe re pe “Oju gbogbo enia nwo o; iwo si fun won li onje won li akoko re” nitoripe Olorun ni ife nwon “Iwo si owo Re, iwo si te ife gbogbo ohun alaaye lorun” **Orin Dafidi 145: 15-16**. Olorun npese fun aini olukuluku eda-alaaye, o si nte ife won lorun, nitoripe o ni’fe won.

**Sise ikawo aiye:** O ti di mimo wipe Olorun ni ife awa enia pupo-pupo debipe o sure fun wa wipe “E ma bi si i, ki e si ma re, ki e si gbile, ki e si se ikawo re; ki e si ma joba lori eja okun, ati lori eiye oju-orun, ati lori ohun alaaye gbogbo ti nrako lori ile” **Genesisi 1: 28.** Ti o ba je wipe Olorun ko ni ife awa eda-enia, ko ni fi wa joba lori gbogbo eda ise-owo Re ninu aiye; lati ma se adari ati olukawo won. Opo kristiani ni ogbon ku fun, ti won si ma nwipe bi Olorun ba ni ife awon, etise ti awon fi wa ni ipo ti awon wa? E wa ni ipo ti e wa lowolowo nitoripe a ni lati dan igbagbo yin wo; atipe olukuluku enia ni

lati ru agbelebu tire. "Emi ti fe nyin" li Oluwa wi. "Sugbon enyin wipe 'ona wo ati ninu kili o fe wa?' E ti gbagbe wipe ohun gbogbo ninu aiye yi , ti Oluwa ni: sugbon o wu Olorun ni o se yan awa kristiani fe, ti o si se wa ni ohun-ini pataki" **Malaki 1: 2.** Bibeli wipe " awa ni iran ti a yan olu-alufa, orile-ede mimo, enia oto; ki awa ki o le fi ola-nla eniti o pe wa jade kuro ninu okunkun sinu imole iyanu re han" **1 Peteru 2: 9.** Olorun se afihan ife ti o ni si wa nipa pipe wa jade kuro ninu okunkun sinu imole aiyeraye Re.

**Jesu Kristi ku fun awa elese:** Iwe mimo wipe "Nitori Olorun fe araiye tobe ge, ti o fi Omo bibi re kansoso funni, ki enikeni ti o ba gba a gbo ma ba segbe, sugbon ki o le ni iye ainipekun" **Johannu 3: 16.** Olorun fihan gbangba, ife ijinle ti o ni fun awa eda-enia, nipa riran Jesu Kristi Omo Re si aiye lati gba araiye la. O fi idi ife re mule fun awa enia wipe, bi a tile je elese Jesu Kristi ti ise Messiah araiye ku fun wa. Iwe Romu wipe "Sugbon Olorun fi ife On papa si wa han ni eyi pe, nigbati awa je elese Kristi ku fun wa" **Romu 5: 8.** Olorun se ipolongo ife ti o ni si awa eda-enia, nipa mimu ki Jesu Kristi Eni-mimo ati Eni-ami-ororo ku fun awa elese ati alai-ye. Nipa eyi li a gbe fi ife Olorun han ninu wa, nitoriti Olorun ran Omo bibi Re nikansoso si aiye, ki awa ki o le ye nipase Re **1 Johannu 4: 9.** Olorun so di mimo, bi on ti ni ife wa to, nipa riran Jesu Kristi Omo Re wa sinu aiye, ki a ba le ti ipase Re ni iye-ainipekun.

**Ko si ife ti o ju eleyi lo:** E jeki a se ayewo finifini, ki ale ri ife-nla ti Baba wa ti mbe ni orun ni si wa; ti o fi fun wa ni ore-ofe lati pe wa ni omo Re. Sugbon awon enia ninu aiye ko dawamo wipe omo Olorun ni awa ise; nitoripe won ko mo Olorun. Baba ti fun wa ni anfani ki a le pe wa ni omo Olorun ati ki a le ka wa gegebi omo Olorun! Atipe omo Olorun ni wa nitoto! Idi ti aiye kofi dawamo ni wipe won ko mo Olorun **1 Johannu 3: 1.** Nitorina, mo o wipe kosi ife ti o tobi ju eyi lo, kosi si enikan ti o fi iru ife ti o lagbara bayi han ri i, gegebi Jesu Kristi ti fi emi Re le ile nitori awa ore Re **Johannu 15: 13.** Ife ti o tobi-julo ti Olorun fihan si araiye ni fifi emi Omo Re Jesu Kristi le'le nitori awa elese.

## Bi a ti se le ni ife Olorun

Orisirisi ona ni a ko sinu Bibeli ti enia le gba lati fihan wipe on ni ife Olorun

Eleda on, besini ao soro nipa won ni kunakuna.

**Pa awon ofin Olorun mo:** O le fihan wipe o ni ife Olorun nipa pipa awon ofin ati awon ase Re mo tokantokan: gegbi a ti ko o wipe, o ni lati pa awon ofin Olorun mo; ki o si jeki igbe-aiye re ati iwa re wa ni ibamu pelu ase Mi, ni Oluwa wi **Lefitiku 22: 31.** Lati isinyi lo, o ni lati gboran, ki o si tele awon ase Oluwa lati ma se won.

E jeki nran wa leti wipe "Enikeni ti o ba ru okan kikini ninu awon ofin wonyi, ti o ba si nko awon enia be, on na li ao pe ni kikini ni ijoba orun: sugbon enikeni ti o ba nse won ti o ba si nko won, on na li ao pe ni eni-nla ni ijoba orun" **Matteu 5: 19.** Nitorina, e mase se alaika awon ofin Olorun si i. Iwo ko gbodo pa eyiti o kere-julo ninu awon ofin na ti i: besini o ko gbodo yan awon kan ninu awon ofin wonyi laayo; ti o je pe awon nikan niiwo yio ma pamo; bikose ki o pa gbogbo won mo. Mase ko enia, tabi gbani-niyanju, tabi se alatilehin fun enia, lati te ofin Olorun loju. Olori ati lajori awon ofin na ni pe ki iwo ki o fi gbogbo aiya re, ati gbogbo okan re, ati gbogbo agbara re, ati gbogbo inu re fe Oluwa Olorun re; ati enikeji re bi ara re **Luku 10: 27.**

**Beru Oluwa, ki o si dekun sise ibi:** Enikeni ti o ba ni ife Oluwa ni lati korira ibi; bibeko onitohun ntan ara re ni: gegebi ese Bibeli "Enyin ti o fe Oluwa, e korira ib: o pa okan awon enia mimo re mo: o gba won li owo awon enia buburu" **Orin Dafidi 97: 10.** Enyin ti o ni ife Oluwa, e ko Satani ati ise re sile. E ko si gbodo fe aiye, ki Olorun ba le gba yin kuro lowo agbara awon enia buburu. Nitorina, beru Oluwa, ki o si ma rin li ona re ni ai-sako-lo; ki o ba le di alabukun-fun **Orin Dafidi 128: 1.** Mase gbagbe wipe iberu Oluwa ni ikorira ibi; irera ati igberaga, ati ona ibi ati enu arekereke **Owe 8: 13.** Enikeni ti o ba wu lati ni ife Olorun ni lati korira ibi, ati iro-pipa, ati igbe-aiye ese, ati ayida-yida.

**Rin pelu Olorun ninu igbagbo:** Laisi igbagbo, ko se se fun enia lati wu Olorun, tabi ba Olorun rin; nitori eniti o ba nto Olorun wa ko le sai gbagbo pe o mbe, ati pe on ni olusesan fun awon ti o fi ara bale wa a **Heberu 11: 6.** O nilo igbagbo ki o to le wu Olorun tabi ni ife Re: gegebi iwe mimo ti o wipe "Abrahamu gba Olorun gbo, a si ka a si ododo fun u: a si pe e li ore Olorun" **Jakobu 2: 23.** Bi o ba fe fi idi re mule wipe o ni ife Olorun, ati pe ore Olorun

ni o, o ni lati rin pelu Re ninu igbagbo.

**Ose Kerindinladota: Osu Kokanla Ojo Kejila, 2017**

**Akori oro: Olorun ni ki o fe kise aiye** – Apa keta

**Eko Bibeli: 1 Johannu 2: 12-17**

Ao tesiwaju ninu eko wa nigbati ao menuba awon eko Jesu Kristi Oluwa ti a ko sinu Bibeli nipa nini ife Olorun.

**Awon eko Jesu Kristi**

Opo enia ninu aiye loni ti ti oju won nipa ti emi si otito, sugbon won la oju si awon ohun asan aiye yi, pelu awon ifekufe re.

**Ni ife Olorun ati enikeji re:** Jesu Kristi mo wipe nini ife Olorun ati omonikeji re ni ona kansoso ti o le mu ki enikeni jogun ijoba Olorun. Nitori eyi ni o se ran awon Aposteli leti, lati ni ife ara won gegebi on se ni ife won, ti on si tun ni ife Olorun. A kowe re wipe "Ofin titun kan ni mo fifun yin, ki eyin ki o fe omonikeji yin; gegebi Emi ti feran yin, ki eyin ki o si le feran omonikeji yin" **Johannu 13: 34**. Ri daju pe o ni ife omonikeji ati Olorun gegebi Kristi ti fi lele. Baba re ti mbe ni orun feran re pupo, nitoripe o ni ife Omo re Jesu Kristi, ti o si gbagbo pe, lodo Olorun li on ti jade wa; ti o si ntele awon ofin re **Johannu 16: 27**. Nitorina, mase ya kuro ni oju ona ododo, beni ki o si di igbagbo re mu sinsin.

**<u>Sa gbogbo ipa re ki o si ni iforiti:</u>** Ohunkohun ti o ba nla koja, tesiwaju ninu ife Olorun; ki o si sa gbogbo ipa re: ri daju pe o se ohun gbogbo ti o leto fun idagbasoke ati itankale ise Oluwa. Baba wa orun fe Jesu Kristi Oluwa wa gidigidi toripe, o sa gbogbo ipa re fun ise Baba re; debipe o fi emi ara re rubo lati gba awa eda-enia la. Iwe mimo wipe "Nitorina ni Baba mi se feran mi, nitoriti mo fi emi mi lele, ki emi ki o tun le gba a" **<u>Johannu 10: 17</u>**.

Ohun ti Olorun nilo lati odo re nipe ki o sa gbogbo ipa re fun ise re: gegebi ese Bibeli ti o wipe "Ifibu ni eniti o se ise Oluwa ni imele, ifibu si li eniti o da ida re duro kuro ninu eje" **<u>Jeremiah 48: 10</u>**. Nitorina, mase se alaika ise Oluwa si i tabi se ise Oluwa basa-basa: ki o maba di eni-egun. Bi o ba nfe ibukun lati odo Oluwa mase fi imele se ise re, sugbon sa gbogbo ipa re fun ise re.

O ni lati sa gbogbo ipa re fun ise-Oluwa, ki o si foriti de opin; nitori o mo wipe "eniti o ba foriti i titi de opin, on na li ao gbala" **<u>Matteu 24: 13</u>**. Ranti wipe bi o ba jiya pelu Kristi, tabi jiya nitori Kristi nipa sise ohun tito, ti o si fe Olorun; nigbana ni ao se o logo pelu re e, ninu ijoba re li orun. Nitorina, mase ka ijiya tabi isoro ti mba aiye re finra si i: toripe ko se fi se akawe ogo ti Olorun yio fihan ninu re **<u>Romu 8: 17-18</u>**.

Fun idi eyi mase beru ijiya isinsiyi tabi awon ohun ti o nbowa jiya re. Kiyesi pe Esu nfi awon enia sinu igbekun ati ide, ki a le dan igbagbo won wo: sugbon iwo se olododo de oju iku, ki a le fi ade iye fun o **<u>Ifihan 2: 10</u>**. So ifo'ya re nu, beni ki o mase beru wahala ti nkoju re lowolowo, nitoripe ao fi ade iye fun o, bi iwo ba se olotito de oju iku.

**<u>Iwo yio gba ere:</u>** Okan lara awon ere ti ao fifun enikeni ti o ba feran Jesu Kristi Oluwa wa; ti o si tele awon eko re nipe ao ma pe iru awon enia be ni omo-lehin- Kristi. Akowe re wipe"Nipa eyi ni gbogbo enia yio fi mo pe, omo-ehin mi li eyin ise, nigbati eyin ba ni ife si omonikeji yin" **<u>Johannu 13: 35</u>**. Ife re si omonikeji re ni ona ti o daraju lati se afihan fun araiye wipe omo-ehin Kristi ni o nitoto. Nitorina, bi o ba fe ki a fi oye omo-ehin da o lola, ni ife Jesu Kristi, ki o si tele awon eko re.

Bi o ba feran mi, pa ofin mi mo, ni Oluwa wi. Nigbana ni Emi o bere lowo Baba, ti yio si fun o ni Olutunu miran ti yio ba o gbe titi lailai **Johannu 14: 15-16**. Bi o ba fe ki Olorun fun o li Olutunu, mase sako kuro ninu awon eko Kristi. Fun aiye re lati gba awon ebun Emi mimo; o ni lati feran Jesu Kristi ati Baba Re. Bi Olorun ba je Baba re, iwo yio feran Kristi, beni iwo yio si bo'la fun u; toripe o wa lati odo Olorun. Ko wa nitori nipa ase tabi ife-inu ti ara re; beni wiwa re ki se nipa ipinnu eniti o ran ara re, bikose pe Baba wa ti mbe li orun li o ran a **Johannu 8: 42**. Ni ife Jesu Kristi, mo o ni Oluwa ati Olugbala re; ki o si fi oyaya gba laaye sinu aiye re; lati fihan gbangba wipe Olorun ni Baba re, besini omo Olorun Olodumare ni iwo ise.

Enikeni ti o ba feran Jesu Kristi ni Baba re yio fe, Jesu paapa yio feran iru enia na; yio si fi ara re ninu aiye onitohun nipa ise-ami ati iyanu. Awon ti won ba li ofin re, ti won ba si npa won mo, awon li o feran re e **Johannu 14: 21**. Bi o ba fe ki Baba wa ti mbe li orun feran re, o ni lati fe Omo Re. Bi o ba fe ki o farahan ninu aiye re nipase ebun Emi mimo, o ni lati pa awon ofin re mo.

**Awon ojuse re:** O je ojuse fun gbogbo enia ti o ni ife Jesu Kristi Oluwa wa lati se awon ase wonyi:

- Se o fe Jesu Kristi ju oro, ati okiki ati awon ohun asan aiye lo? Bi o ba ri be " Ma bo awon odo-aguntan re" ki o si ma pese fun won.
- Se o ni ife Jesu Kristi? Bi o ba ri be "Ma bojuto awon aguntan re" ma se oluso-aguntan won tabi bojuto won.
- Se o feran Jesu Kristi? Bi o ba ri be "Ma bo awon aguntan re" ki o si ma bojuto aini won **Johannu 21: 15-17**. Enikeni ti o ba feran Jesu Kristi Oluwa wa ni lati mu gbogbo awon ase ti a menuba yi se.

Akainiye enia ninu aiye ni ko ni ife Olorun, sugbon ti won ni ife awon adidun ati awon ohun mere-mere aiye yi. Idi niyi ti iwe mimo se so wipe "Eyi ni idajo na pe, imole wa si aiye, awon enia si fe okunkun ju imole lo, nitoriti ise won buru." A gbe idajo yi i lori otito, wipe imole Olorun wa sinu aiye , sugbon awon enia feran okunkun ju imole lo , nitoripe awon iise won je kikida ibi **Johannu 3: 19**. Bi o ko ba feki a da o lejo pelu aiye, ti iwo kosi

fe segbe pelu re e; mase ni ife aiye, sugbon ni ife Olorun. Mase fe okunkun ti yio mu idajo Olorun wa si ori re, sugbon fe imole ti yio fun o ni idalare.

Awon enia ni lati ronu-jinle nipa ese Bibeli ti o wipe "Beni ki iwo ki o ko wa lati ma ka iye ojo wa, ki awa ki o le fi okan wa sipa ogbon" **Orin Dafidi 90: 12**. O ni lati mo wipe aiye yi fun igba die ni. O ni lati ni oye wipe igba kukuru ni o ni lati lo ninu aiye. Bere sini ka ojo-ori re lori ile alaaye, ki o ba le dagba ninu ogbon ki o si je ologbon. Nitorina, mase lo iyoku ninu ojo-aiye re lati feran aiye ati awon ifekufe re.

## Duro ninu ife Olorun

Enikeni ti o ba duro ninu ife Olorun ni ki yio yese titi-lai, irufe awon enia be ni yio joba pelu Eleda won titi aiye.

**Awon ti o duro ninu ife Olorun ni yio ye e:** Awon enia ni lati mo pe "Ko si eniti o le sin oluwa meji: nitori yala yio korira okan, yio si fe ekeji; tabi yio faramo okan, yio si yan ekeji ni iposi. Eyin ko le sin Oluwa pelu mammoni" **Matteu 6: 24.** O ti ka ninu iwe mimo wipe, o ko le sin Oluwa pelu mammoni; eyiti o tumo si wipe o kole ni ife Olorun, ki o si tun feran owo tabi ki o feran oro, tabi ki o feran okiki tabi ipo. O ko le fe Olorun, ki o si tun je eru-sin fun awon ohun aiye. Sugbon tesiwaju nipa jijoko ninu ago Oluwa titi-lai, gbeke re le e, ki o si fi iye-apa Oluwa se ibi abo re: ki abo Oluwa ba le daju lori idile re ati ki a le yanju awon isoro re **Orin Dafidi 61: 4.** Duro girigiri ninu ife Olorun ati ninu ago Re, ki o ba le duro lailai; ki o si ba joba titi aiyeraye, gegebi ese Bibeli ti o wipe "Awon ti o gbekele Oluwa yio dabi oke Sioni , ti a ko le si ni idi bikose o duro lailai" **Orin Dafidi 125: 1.** O ku si o lowo: yala ki o ni ife Olorun ki o si duro lailai tabi ki o feran aiye ki o masi duro pe titi. A gbadura wipe eyiti o dara ni iwo yio muse e.

Ronu wipe gegebi Baba wa ti mbe li orun ti fe Jesu Kristi, beni on na feran wa; nitorina, a ni lati duro ninu ife Re. Ko si awawi lati mase duro ninu ife Re, eyiti yio muki Oluwa fun wa ni ere ni aiye yi ati ni aiye ti mbo **Johannu 15: 9.** Nitorina, e jeki a duro lailai ninu ife Oluwa wa, nitori titobi ati nla ni ife ti o ni fun wa.

**E mase jeki a tan yin:** Niwon igbati oye ku fun awa enia, opo ninu wa ko mo pataki ife ati riri ki a ni ife Olorun. Nipa ola-nla ogbon ati imo Olorun, o ni oye riri ati pataki ife si i iwa-laaye awa eda-enia **Romu 11: 33.** Idi niyi ti awa fi mo, ti a si gba ife ti Olorun ni si wa gbo. A tun ni lati mo wipe ife ni Olorun; eniti o ba ngbe ninu ife o ngbe ninu Olorun, ati Olorun ninu re **1 Johannu 4: 16.** Eri ti wa wipe a ni lati ni oye iru ife ti Olorun ni fun wa, ki a ba le fi emi-imore han a, ki a si faramo o, pelu igbekele ninu ife-nla yi. O ni lati tesiwaju ninu ife Olorun toripe, Olorun ni ife, ki o si duro ninu ife Re titi lai.

Siwaju si, o ni lati ya kuro ninu ese ati aisedede nitoripe, "Enikeni ti o ba ngbe inu re ki idese; enikeni ti o ba ndese ko ri i, beni ko mo o" **1 Johannu 3: 6.** Bi o ba fe fihan wipe o duro o duro ninu ife Olorun atipe oye re ye o: o ni lati sa fun ese ati iwa-kiwa; beni o ko gbodo yan iwa-ibaje laayo. O ni lati gbe igbese ni kiakia, toripe, yala o fe tabi o ko fe, o gbagbo tabi o ko gbagbo, aiye yi nkoja lo: Igba kukuru ti o ni lati lo ni ile alaaye, o ni lati se atunse. A kowe re wipe "Aiye yi nkoja lo, ati ifekufe re; sugbon eniti o ba nse ife Olorun ni yio duro lailai" **1 Johannu 2: 17.** Niwon igbati aiye yi yio koja-lo pelu gbogbo ifekufe ati iwakuwa re; akoko ti to fun o, lati feran Olorun ki o si ma se ife re; ki o ba le duro lailai.

**Duro ninu Imole:** Jesu Kristi ni imole aiye, enikeni ti o ba fe e, ti o si to o lehin ki yio rin ninu okunkun; sugbon yio ni imole iye **Johannu 8: 12.** Bi o ko ba fe ki okunkun bori re, duro ninu imole ti ifunni ni iye: toripe, Jesu Kristi wasi aiye gegebi imole lati tan ninu aiye to sokunkun; ki enikeni ti o ba gba a gbo ki o mase wa li okunkun, sugbon ki won le ni imole aiyeraye **Johannu 12: 46.** Bi o ko ba fe wa ninu okunkun birimu-birimu, o ni lati ni ife Olorun ati omonikeji re; gegebi ese yi "Eniti o ba feran arakunrin re, o ngbe ninu imole, ko si si ohun ikose ninu re" **1 Johannu 2: 10.** Bi o ko ba fe kose tabi ki o muki awon elomiran subu sinu ese tabi ki won sako kuro niwaju Olorun; o ni lati feran Olorun ati enikeji re gegebi ara re.

O ni lati se awokose Jesu Kristi ninu iwa ati ise e; toripe eniti o ba wipe on ngbe ninu Jesu Kristi, on na pelu si ye lati ma rin gegebi Jesu ti rin **1 Johannu 2: 6.** Mase feran okunkun, sugbon feran imole ki o si duro ninu re: lati fihan wipe o duro ninu Kristi.

Ojuse re ni lati pa ofin Jesu Kristi mo; ni igbana ni iwo yio duro ninu ife re gegbi on na ti pa ofin Baba re mo, ti o si duro ninu ife Re **Johannu 15: 10.** Mase gbagbe wipe ko si alaigboran kan ti yio wo ijoba Olorun, torina ni ife Re ki o si pa ofin Re mo.

**Ose Ketadinladota: Osu Kokanla Ojo Kokandinlogun, 2017**

**Akori oro: Olorun ni ki o fe kise aiye** – Apa Kerin

**Eko Bibeli: 1 Johannu 2: 12-17**

Eko yi ntesiwaju nigbati ao soro lori awon ofin Oluwa ti a ko sinu Bibeli

nipa bi enia se gbodo ni ife Oluwa Olorun.

## Awon Ofin Oluwa

Opolopo awon ofin Oluwa ni a ko sinu Bibeli, sugbon ohun ti o se'ni la'nu ni pe, nigbati enia si wa laaye nikan ni o ni ore-ofe lati ni ife Olorun. Nitorina, mase fi akoko sofo; se atunse nigbati ore-ofe si mbe fun o, ki akoko to koja lo.

**Ofin akoko ati Ofin nla:** Jesu wipe "Ki iwo ki o fi gbogbo aiya re, ati gbogbo okan re, ati gbogbo inu re, fe Olorun Oluwa re. Eyi li ekini ati ofin nla. Ekeji si dabi re, Iwo fe omonikeji re bi ara re. Ninu awon ofin mejeji yi ni gbogbo ofin ati ati woli ro mo" **Matteu 22: 37-40.** Bi Jesu Kristi ba fi ese re mule pe awon ofin mejeji yi ni ako-ja gbogbo ofin to'ku, ti gbogbo ofin ati woli si sinmi le e; o se pataki ki o mase fi oju pa ofin yi re: mase lora tabi ki o kehin si ati-fe ofin yi, bikose ki o faramo tipe-tipe. Fun idi eyi ni Jesu Kristi se fun wa ni ofin wipe eniti o ba feran Olorun gbodo feran awon arakunrin ninu Oluwa **1 Johannu 4: 21.** Lati fihan wipe o feran Olorun, o gbodo feran awon ara wa ninu Oluwa: nipa sise eyi, awon enia yio mo wipe o feran awon omo Olorun; nitoripe o feran Olorun, beni o si npa ofin Re mo **1 Johannu 5: 2.** Okan ninu awon ona lati jeri wipe o ni ife Olorun, o si npa ofin Re mo ni ki o ni ife omonikeji re bi ara re. "Nitorina, kiyesara re gidigidi, ki o fe Oluwa Olorun re" **Josua 23: 11.** O ni lati ma funra ki o si ma sona lati ri daju pe o feran Olorun.

**Ma rin gegebi ofin Oluwa, ki o si ma pa a mo:** Ojuse re ni lati fe Oluwa Olorun re, ki o si ma pa ase re ati itoni re ati oro re mo. A kowe re wipe "Nitorina, ki iwo ki o fe Oluwa Olorun re, ki o si ma pa ilo re, ati ilana re, ati idajo re, ati ofin re mo, nigbagbogbo" **Deuteronomi 11: 1.** Nitorina, ni ife Olorun, ki o si pa ofin re mo. A ni lati mo wipe ife tumo si pe ki pa ofin Olorun mo, gegebi a ti gbo lati ibere-pepe. Torina, rin gegebi ofin Oluwa; jeki ilana ati eko Olorun ma se itoni re. Ri daju pe igbe-aiye re wa ni ibamu pelu awon ofin Oluwa **2 Johannu 1: 6.** Niwon igbati ife tumo si pe, ki a se ohun ti Olorun so fun wa, e jeki a feran omonikeji wa gegebi Oluwa ti pase fun wa lati ibere.

Mase gbagbe wipe nini ife Olorun tumo si pe ki a pa ofin re mo; beni ofin re ko nira. Ri daju pe o ko iwa pipa ofin ati eko Olorun mo; nitoripe, won ko

nira lati pamo **1 Johannu 5: 3.** O ni lati jeki okan re dogba pelu awon ilana Oluwa, pa ofin Re mo; ki o si ma kiyesi oro Re, niwon igbati won ko soro lati pamo.

**Mase ni ife enia ju Olorun tabi gbe enia ga ju Olorun lo**: Ni aiye ode oni, opo enia ni won feran omo, tabi oko, tabi aya, tabi obi, tabi ebi won, ju Olorun lo. Ogoro enia si gbe ise-oojo won ga ju Olorun lo, nigbati akainiye enia si fe lati ma lo si awon ibi-apejopo ohun asan aiye bi ibi-apeje, ati ibi ere-idaraya, ju ipejopo-esin lo. Jesu Kristi wipe "Eniti o ba feran baba tabi iya ju mi lo, ko ye ni temi: eniti o ba fe omokunrin tabi omobinrin ju mi lo , ko si ye ni temi" **Matteu 10: 37.** Nitorina, o ko gbodo feran ohun-elemi tabi ohun ti ko ni emi ju Oluwa Olorun re lo; beni o ko gbodo gbe won ga ju Olorun re lo.

**Feran Olorun ni aisetan:** Gbogbo onigbagbo ni lati ni ife-aisetan si Olorun; ki o ba le da abo bo won, ki o si lo'ra emi won: nigbati Olorun ba nse idajo awon enia buburu, awon wonyi ki yio ko'pa ninu re **Orin Dafidi 31: 23.** Feran Oluwa Olorun tokantokan, ki a ba le lo'ra emi re ninu aiye; beni ao si fun o ni ere, ni aiye ti mbo fun iduro-sinsin re.

## Awon iyorisi aini ife Olorun

Awon enia ti ko feran Olorun yio ni opolopo idojuko ti a ko sinu Bibeli, beni ao si soro nipa won ni kunakuna.

**Ewu igba-ikehin:** A ti se ikilo fun o ninu Bibeli wipe, ni igba-ikehin oniruru ohun-ibi ni yio ma sele ninu aiye; eyi yio si mu ki ife opolopo enia di tutu. Lowolowo, a ti wa ni igba-ikehin; ese ndi pupo si i, iwa-ika ati iwa-aibikita tunbo ngbile si, beni iwa aigboran ati iwa ibaje ndi gbigboro ni ona ti enikeni kole daa duro. Se iwo wa lara awon ti ife won ti tutu? Bi o ba ri be, o ni lati ji-giri, ki o si gbe agbara Olorun wo **Matteu 24: 12.** Igba-ikehin ki se awawi fun o lati dekun nini ife Olorun; tabi lati dekun nini ife omonikeji re: o yeki o je ohun ti yio mu o ni itara, nitoripe, akoko kukuru ni o ni ninu aiye. Ife re ko gbodo re'le, tori awon isele ninu aiye: nitorina, tesiwaju lati ma fe Olorun re ati omonikeji re lai-bojuwehin.

Ni ode oni, awon enia feran igbori-yin lati odo eda-enia ju lati odo Olorun lo; gegebi awon Farisi ti a ko sinu Bibeli. Opo enia ni won fe ika-ye eda-enia ju ti Olorun lo: beni akainiye enia ni won nfe ogo lati odo eda-enia ju ogo ti o wa lati odo Olorun lo **Johannu 12: 43**. Mase se bi awon agabagebe wonyi; feran Olorun, ki o si fi okan re si ika-ye ati ajosepo ti mbe larin iwo ati Olorun.

**Aiye le korira re:** Okunkun mo wipe atipo ati aririn-ajo ni awa onigbagbo je ninu aiye; atipe orun ni ilu-ibile wa. Awon wonyi mo wipe awa ki ise ti aiye: ibasepe awa ise ti aiye; aiye iba feran wa, won a si se itoju wa gegebi okan lara awon tire. Aiye korira wa toripe awa ki ise ti aiye, niwon igbati Jesu Kristi ti yan wa kuro ninu aiye **Johannu 15: 19.** Tori kini o se ni lati ni ife aiye ti o korira re? Nitorina, mase feran aiye ti ise tanadi re, bikose ki o fe Olorun pelu gbogbo ipa ati agbara re.

**Mase ni ife emi re bikose ki o fe Olorun:** Iwe mimo wipe "Eniti o ba fe emi re yio so o nu; eniti o ba si korira emi re li aiye yi ni yio si pa a mo titi fi di iye ainipekun." Enikeni ti o ba feran emi re, yio papa so o nu nipase iku; sugbon enikeni ti ko feran emi re ninu aiye yi, nitori ati pa ofin Olorun mo; awon wonyi ni yio pa emi won mo titi-lai **Johannu 12: 25.** Mase fe aiye, bi o ko ba fe segbe pelu aiye; mase fe emi re bi o ko ba fe so o nu, sugbon fe Olorun.

Yio dara bi awon onigbagbo ba le se bi awon asegun ti yio se ajoyo ninu orun: awon ti won segun Esu nipase eje Odo-Agutan ati oro eri won; nitoripe won ko feran emi titi de iku **Ifihan 12: 10-11.** Bi o ba fe bori Satani nipase eje Odo-agutan ati oro eri re; mase feran emi re, sugbon feran Olorun; beni mase beru lati ku nitori ipolongo ati itankale ise Oluwa.

**Eegun ati iku nduro de enikeni ti ko fe Kristi:** Eegun aiyeraye nduro de okan kokan ti ko fe Jesu Krisit tabi gboran si ase Re. Enikeni ti ko ba bu ola fun Jesu Kristi, ki o si gbagbo ninu Oluwa ati oro on eko Re ni ao fi gegun titi lai **1 Korinti 16: 22.** Bi o ko ba fe di eni-egun, feran Jesu Kristi, mase feran aiye.

Enikeni ti o ba korira Oluwa fe iku: iru awon enia be nfi iku sere, beni won

nrin ni bebe iku; enikeni ti o ba se Oluwa, o se okan ara re nika **Owe 8: 36.** Bi o ko ba fe ifarapa, mase se Oluwa, sugbon wa a tokantokan.

## Ko eko lara awon isele wonyi

O dara bi o ba ko eko lara iriri tabi asise elomiran, toripe bi iru isele yi ba sele si o, iyorisi re le je ohun ti o lagbara; ti o si le muki enia so ohun ti kole ri pada nu, tabi ki o fa ipa-buburu ti ako le mubosipo sinu aiye re.

**Kosi ohun ti o poju tabi tobiju lati se fun Oluwa:** O ni lati mo ninu okan re pe, kosi nkankan ninu aiye yi ti o poju tabi tobiju lati se fun Oluwa. Bi o ba di sise ise Oluwa, nini ife re, ati titele ofin re; gbaradi lati lo ohun gbogbo ti o ni fun u. Baba-nla wa Abrahamu setan, lati fi omo re Isaaki rubo, gegebi ase Oluwa. Lotito a da emi Isaaki si i; Abrahamu fi apere le'le, nitoripe o ni ife Oluwa Olorun; o si beru Re **Genesisi 22: 1-3.** Niwon igbati o je pe ohun gbogbo ti o ni ninu aiye ti odo Olorun wa; mase ko nigbakugba ti o ba bere ohun kan lowo re: mase se aigboran si ofin Re; sugbon lo ola, ati agbara, ati ogbon, ati akoko re lati sise fun Oluwa; ki o ba le di mimo pe o feran Oluwa.

**Mase pataki awon ohun aiye:** Opolopo enia ni won pataki ohun asan aiye ti yio segbe; sugbon awa fe ki iwo je ologbon, ki o maba darapo mo iru awon eda wonyi. Oba Solomoni feran awon ajoji obinrin, o si pataki won ni igba ogbo re: ni eyiti o fi ye ki o feran Olorun ti o sanu fun u, ki o si pataki Re. Iwa yi si fa isubu re ni iwaju Olorun **1 Awon oba 11: 1-2.** Bi o ko ba fe ki ohun aiye so o di eru won, mase feran won tabi pataki won.

**Fi ogbon kun irinajo re:** Jesu Kristi Oluwa fi ogbon lo irinajo re; beni o bori gbogbo idanwo Esu. Bi a ba le dan Jesu Kristi wo, kosi eniti adanwo kole deba. Nitorina, gbaradi lati bori idanwo nigbakugba ti o ba de **Matteu 4: 8-10, Luku 4: 5-8.** Fe Olorun, ki o si fi ogbon lo irinajo re; ki o ba le bori idanwo ti o nla koja lowolowo.

## Se ipinnu rere loni

Se ipinnu lati ni iwa ti o dara niwaju enia ati niwaju Olorun. Ranti pe nini ife Olorun ati pipa ofin Re mo gbodo je koko ati ai-gbodo-mase fun o titi di ojo

iku re.

**O ni idi pataki lati yin Oluwa:** Pinnu lati yin Oluwa fun gbogbo ore ati anu Re ninu aiye re. O ni lati se ipinnu lati fe Oluwa, nitori ti O ngbo ohun re ati adura re **Orin Dafidi 116: 1.** Mase dekun nini ife Olorun, sugbon duro-sinsin ninu iwa ododo yi. Nitoripe o feran Olorun ni o mu ki on na ma gbo igbe re ni gbogbo igba; ti o si nfun o ni esi-ayo lori awon ebe ati adura re.

**Fe Olorun ati awon ibi-mimo Re:** O ni lati pinnu lati fe ibujoko ile Oluwa, ati ibiti ola-nla ogo Re ngbe. Se ipinnu lati ma pese fun ile-ijosin Oluwa gegebi ibukun ti o fifun o. Pinnu ninu okan re lati ma bojuto aini awon oke-mimo ati tempili nibiti ogo-ola Re fidi-kale si **Orin Dafidi 26: 8.** O gbodo yonda eyikeyi ohun-ini re fun ise ile-mimo Oluwa, bikosebe, iwo ko feran Oluwa. Se afarawe oba Solomoni ti o pinnu lati ko ile kan fun oruko Oluwa **2 Kronika 2: 1.** O ni lati ko'pa ninu kiko ile Oluwa, o di dandan ki o dasi kiko ile mimo Re, beni o gbodo fi nkan sile lati ko'le fun Oluwa.

**Fe Olorun ati omonikeji re:** Rutu se ipinnu rere, beni a si fun ni ere-nla; nitori o feran Olorun ati iya-oko re. Ko ya kuro lodo iya-oko re, lehin iku oko re, sugbon o mu eleyi gegebi iya re. Nigbati Orpa orogun re pada sodo awon enia re, nse ni Rutu faramo Naomi iya-oko re. Ipinnu Rutu si mu ki o so oro wonyi jade pe "Mase ro mi lati fi o sile, tabi lati pada kuro lehin re: nitori ibiti iwo ba lo, li emi o lo; ibiti iwo ba si wo, li emi o wo; awon enia re ni yio ma se enia mi, Olorun re ni yio si ma se Olorun mi" **Rutu 1: 1-18**. Se o ni iru ipinnu rere bayi, lati fe Olorun ati omonikeji bi ara re? Se iwo yio duro-sinsin nigbati nkan bale-koko bi oju eja, ti o si wani ikorita ireti-pin?

**Kosi ohun ti o gbodo ya o kuro ninu ife Kristi:** Mase jeki ohunkohun ya o kuro ninu ife Jesu Kristi Oluwa wa. Mafi aye gba aja-lu, tabi ebi, tabi ibanuje, tabi itoro-je, tabi inira lati mu ki o da'le tabi se ife Oluwa. Gegebi a ti kowe re wipe "Tani yio ha ya wa kuro ninu ife Kristi? Iponju ni, tabi wahala, tabi inunibini, tabi iyan, tabi ihoho, tabi ewu, tabi ida?" **Romu 8: 35.** Ikankan ninu awon ohun ti ka sile yi, tabi ohun miran tabi enikeni ko gbodo mu ki o da ife Kristi. O di dandan pe ohun elemi ati ohun ti ko ni emi ko gbodo ya o kuro ninu ife Jesu Kristi Oluwa.

**Ose Kejidinladota: Osu Kokanla Ojo Kerindinlogbon, 2017**

**Akori oro: Olorun ni ki o fe kise aiye** – Apa Karun

**Eko Bibeli: 1 Johannu 2: 1**

Ao tesiwaju ninu eko yi, nigbati ao menuba awon ikilo Oluwa ti a ko sinu

Bibeli; ki awa onigbagbo ba le kiyesara ninu aiye.

**Awon ikilo**

Awa fe ki eyin mo wipe, ki Olorun to mu ijiya tabi idajo wa, yio ti se ikilo ni opolopo igba. Nitorina, fi eti si awon ikilo wonyi, ki o si kiyesara ninu ohun gbogbo ti o ba nse; ri daju pe o ko ni ife aiye, sugbon ni ife Olorun tokantokan.

**Ni ikehin ojo:** Gegebi a ti menuba teleri wipe, a ti wa ni igba ikehin, ti Bibeli na si jeri si wipe ni ikehin ojo igba ewu ati igba isoro yio de. Awon enia yio je olufe ti ara won ati onimo ti ara won nikan. Won yio je olufe owo ati wobia, ti ife ati ko ola jo se koko si i. Awon enia yio je afunnu, agberaga ati alafojudi. Won yio je asoro-buburu ati asoro-odi: won yio je asaigboran si obi, alai-lope ati alaimo **2 Timoteu 3: 1-2.** Gbo ikilo Oluwa: mase je olukiyesi ti ara re nikan tabi olufe owo. O ko gbodo je onibaje-enia, tabi jegudu-jera, tabi wobia, tabi alafojudi. O ko gbodo ri Olorun fin tabi se aigboran si awon obi re; mase je alaimore si Olorun, sugbon bowo fun awon ohun mimo Re.

Ya ara re kuro ninu aiye ki o masi se ko ife Olorun sile; jeki awon enia ri iyato wipe, iwo ko si lara awon enia ti won feran aiye ati ifekufe re **2 Timoteu 4: 10.** Mase dabi arakunrin Dema ti o ko Paulu sile nitori o nfe aiye isisinyi; sugbon jeki ife Olorun se koko ninu aiye re. Nitorina, jeki o di mimo fun o wipe, bi o ko ba le ko ohun gbogbo ti o ni sile, iwo ko le se omo-ehin Kristi ni iwe mimo wi **Luku 14: 33.** Yonda aiye re ati gbogbo ohun-ini re ti o ni ninu aiye fun Oluwa; fi igbe-aiye re atijo sile, ki o si ko Satani ati ise-owo re sile: nigbana ni Oluwa yio ka o ye, gegebi omo-ehin re.

**Ife Olorun ki igbe ninu iwakiwa:** Ife Olorun ki igbe ninu eniti ko ran omonikeji lowo tabi ki o tu omonikeji lara pelu awon ohun-ini re. Enikeni ti o ba ni awon ohun-alumoni tabi awon ohun-ini, ti o si ri awon onigbagbo bi tire ninu aini, ti kosi sanu fun won nipa bibojuto aini won, ko mo Olorun; beni ife Olorun ko gbe ninu iru enia be. A kowe re wipe, “Sugbon eniti o ba ni ohun ini aiye, ti o si ri arakunrin re ti ise alaini, ti o si se ilekun iyonu re mo o, bawo ni ife Olorun ti ngbe inu re?” **1 Johannu 3:17.** Lo gbogbo ohun

ini re ninu aiye lati sise fun Oluwa ati lati pese fun aini omonikeji re; ki awon enia le mo wipe ife Olorun ngbe ninu aiye re. Kiyesara ki o maba di elegbe awon oniwa-buburu ti won sote si imole, ti won si ko o; nitoripe won ko mo ipa ona re, beni won ko duro nipa ona re **Jobu 24:13.** Ohun ti o le muki o mase di olote niwaju Oluwa, ni ki o ni ife Olorun ati omonikeji re.

**O kole tan Olorun:** Ninu aiye loni, opo enia ni won nfi ife han nipa ori-ahon nikan; sugbon ti okan won ntele ere-ijekuje ati wobia. Akainiye enia ni won ma nsoro didun nipa bi won tise ni ife Olorun to, sugbon ti o je wipe nitori kini ao je, kini ao mu, kini ao fi bora ati imotara-won-nikan ni. Olorun kilo fun Esekieli nipa iru awon enia wonyi, ti won lero wipe awon le tan Olorun **Esekieli 33: 31.** O rorun lati tan enia, sugbon o kole tan Olorun, nitoripe o mo gbogbo ero-okan re. Idi niyi ti Jesu Kristi se wipe “Sugbon emi mo nyin pe, enyin tikaranyin ko ni ife Olorun ninu nyin” **Johannu 5: 42.** Mase tan ara re, ki o lero wipe o ntan Olorun, sugbon se atunse loni, ki akoko to koja lo.

## Awon anfani nini ife Olorun

Akankatan ni awon anfani ti ao fifun enikeni ti o ba fe Olorun. Ao ka die lara awon anfani yi lesese gegbi a ti ko sinu Bibeli:

- Olorun yio sanu fun o, yio si muki ogo re farahan lara re **Eksodu 20:6.**
- Olorun yio pa majemu ati anu mo fun o, ti o ti bura fun awon baba re: On o si fe o, yio si bukun fun o, yio si mu o bisi i: on o si bukun omo inu re, ati eso ile re, oka re ati oti-waini re, ato ororo re, ibisi malu re, ati awon omo agbo-aguntan re. Iwo yio je eni ibukun ju gbogbo enia lo: ki yio si ako tabi abo ninu ile re ti yio yagan, tabi ninu ohunosin re. Oluwa yio si gba arun gbogbo kuro lodo re, ki yio si fi okan ninu arun buburu Egipti, ti iwo mo, si o lara, sugbon on o fi won le ara gbogbo awon ti o korira re **Deuteronomi 7: 12-15.**
- Olorun yio fun o li ojo ile re li akoko re, ojo akoro ati ojo arokuro, ki iwo ki o le ma ko oka re, ati oti-waini re, ati ororo re sinu ile. Olorun yio si fi koriko sinu papa re fun ohunosin re, ki iwo ki o le jeun ki o si yo **Deuteronomi 11: 13-15.**
- Olorun yio le gbogbo awon ota re kuro ni agbegbe re, on o si fi awon ohun ini awon alagbara ti o korira re fun o. Ibi gbogbo ti atelese re ba te

yio je tire, iwo yio si ni agbegbe nla. Ko si okunrin kan ti yio le duro niwaju re: Oluwa Olorun re yio fi iberu re ati ifoya re sara gbogbo enia ni ibikibi ti o ba lo, jakejado agbaiye **Deuteronomi 11: 22-25.**

- Olorun yio pa o mo kuro ninu ewu gbogbo, yio si da emi re si i **Orin Dafidi 145: 20.**
- Olorun yio fi enia ropo re ati enia dipo emi re **Isaiah 43: 4.**
- Baba wa ti mbe li orun yio feran re; Kristi ati Baba re yio si to o wa, nwon o si se ibugbe nwon pelu re,nwon o si ma ba o gbe **Johannu 14: 23.**
- Olorun yio fe o, ao se o logo, beni ao se asepe lori oro aiye re: Iwo yio wa ni odo Jesu Kristi ti iwo o si ma ba joba titi aiyeraye **Johannu 17: 22-24.**
- Ohun gbogbo yio sise po si rere fun o **Romu 8: 28.**
- Olorun ti pese sile fun o, awon ohun ti oju ko riri, ti eti ko gbo ri, ti enikeni kosi ro ninu okan re ri **1 Korinti 2: 9.**
- Olorun mo o, beni iwo na si di mimo fun u **1 Korinti 8: 3.**
- Olorun yio bukun fun o, yio si fun o ni ade iye eyiti o ti se ileri **Jakobu 1: 12.**
- Olorun ti yan o se oloro ni igbagbo, ati ajogun ijoba aiyeraye Re **Jakobu 2: 5.**
- Olorun yio so ife Re di pipe ninu re, ki o le ni igboya li ojo idajo **1 Johannu 4: 17.**

Lakotan, mase fe aiye ti o kun fun ese yi, ti o si nmu enia kolu Olorun ati awon ilana Re: mase feran awon ohun ti mbe ninu aiye tabi awon ohun ti aiye nfe lati fifun o, nitoripe bi enikeni ba feran aiye, ife ti Baba ko si ninu re **1 Johannu 2: 15.** Bi o ko ba fe aiye sugbon ti o fe Olorun, on yio si wo ifasehin ati ainigbagbo re san. Olorun yio fe o lofe pelu ife aisetan; ibinu re yio yi kuro lodo re, ti iwo ko sini ri ibinu re mo titilai **Hosea 14: 4.** Bi o ba fe ki Olorun wo aisotito ati iwakiwa re san, mase ni ife aiye-ese yi. Bi o ba fe ki Olorun fe o pelu ife ailopin, feran Eleda re tokantokan.

**The Seal: 1 Johannu 3: 18:**

E mase je ki a fi oro tabi ahon feran, bikose ni ise ati li otito.